Tọ́jú Rẹ̀ fún Ìkẹ́kọ̀ọ́

Gé e, ká a sí méjì, kó o sì tọ́jú rẹ̀

RÚÙTÙ

KÁÀDÌ BÍBÉLÌ 3

ÌBÉÈRÈ

A. Parí ọ̀rọ̀ yìí tí Rúùtù sọ fún Náómì: “Àwọn ènìyàn rẹ ni yóò jẹ́ . . .”

B. Báwo ni Rúùtù ṣe jẹ́ àpẹẹrẹ rere fún àwọn tó ń tọ́jú àwọn alálàsàn àti àwọn arúgbó?

D. Fi ohun tó yẹ sínú àwọn àlàfo yìí. Rúùtù fẹ́ _____ ó sì di ìyá ńlá fún _____ àti _____.

98 S.K. — Ọdún tí a ko ìwé tó kẹ́yìn nínú Bíbélì

1 S.K.

Ó gbé ayé ní ṅkan bí ọdún 1,200 Ṣ.Ṣ.K.

4026 Ṣ.Ṣ.K. — Ọdún tí a dá Ádámù

RÚÙTÙ

ÌSỌFÚNNI ṢÓKÍ Ọmọ ilẹ̀ Móábù tó jẹ́ olóòótọ́ ni. Opó ni, àmọ́ ó dúró ti Náómì tó jẹ́ ìyá ọkọ rẹ̀ tó ti di arúgbó. Ìfẹ́ tí kì í yẹ̀ tí Rúùtù ní fún Náómì àti bó ṣe pinnu pé Jèhófà ni òun yóò máa sìn mú kó ní ìgboyà láti fi ìlú ìbílẹ̀ rẹ̀ sílẹ̀, kó sì lọ máa gbé ní Bẹ́tílẹ́hẹ́mù. Àwọn èèyàn sọ fún Náómì pé: “Aya ọmọkùnrin rẹ . . . sàn fún ọ ju ọmọkùnrin méje lọ.”—Rúùtù 4:14, 15.

ÌDÁHÙN

A. “. . . ènìyàn mi, Ọlọ́run rẹ ni yóò sì jẹ́ Ọlọ́run mi.”—Rúùtù 1:16.

B. Rúùtù ní ẹ̀mí ìfara-ẹni-rúbọ, ó sì máa ń ṣiṣẹ́ kára.—Rúùtù 2:7, 10-12, 17; 3:11.

D. Bóásì, Dáfídì Ọba, Jésù Kristi.—Mátíù 1: 5, 6, 16.

www.jw.org © 2011 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania